# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV 857 LAG SATURDAY FERUARY 15th — FEBRUARY 22nd 1963 KỌBỌ MEJI


Oro Behin Yo

# Omo Ile Iwe Kan Riran Si Awon Ti O Ku Iku Ojiji Ninu Sosi

CUENCA (SOUTH AMERICA) — Arẹwa ọmọbinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Josephine ti o nlọ si ilewe awọn Aguda ni Quenca, Ecuador (South America) nibiti iṣẹlẹ nla kan ti ṣẹ ni ijẹrinla nigbati nwọn n ṣ e akanṣe isin idupẹ kan lọwọ ti ogunlọgọ awọn ti o pe si ile isin na lati ba obinrin Padi kan yọ, ayọ si ọrun apapandodo, ni a gbọ wipe o ,la a l a, o r i "iran" si gbogbo awọn ti o ku iku ojiji na lọrun wipe nwọn gba wọn tọwọ tẹsẹ, nwọn si wọ aṣọ ala (aṣọ funtun). Ọmọge Josephine ni nigbati on ri awọn oku na nibiti nwọn gbe wa, o dabi ẹnipe ki on dapọ mọ wọn.

Irohin ti a gbọ nipa iṣẹlẹ ti o ṣẹ ni ilewe Padi na ni wipe ẹnikan ninu awọn Padi obinrin ti o nkọ awọn ọmọbinrin t i nwọn f ẹ ṣe i ṣ ẹ SISITA (Sisiter) ni nwọn mba ṣe ajọyọ ọdun mẹdọgbọn (Jubili) ti o ti nṣe iṣẹ Padi rẹ ni ilu na; nwọn si ba a lọ ṣe isin-idupẹ ni Ṣọṣi wọn. Awọn t i o wa ninu ṣọṣina nlọ bi adọtalenirinwo enia – gbogbo wọn si jẹ ọmọ ilewe Obinrin ati awọn padi olukọ wọn.

Nwọn nṣe isin yi lọwọ ni ogiri Ṣọṣi ti nwọn pejọ si na lojiji ti o si wo luwọn mọlẹ, enia mẹrinlelọgọrun ni nwọn ku bamubamu sibẹ. Awọn ṣọja ati awọn ọlọpa ilu na ni nwọn pe wa sibẹ ti nwọn wa nko oku enia ati awọn ti ogiri na ti ṣe leṣe kuro nibẹ.

Ọjọ keje ti awọn oku na ku iku ojiji yi ni Omidan Josephine ti Ọlọrun yọ ninu ewu iku na ni on la ala ri gbogbo awọn oku na ti nwọn wọ aṣọ-funfun gboo ti nwọn nkọrin ninu i l e daradara kan. Omidan na ni bi ibiti on gbe ri awọn oku na ni nwọn npe ni ỌRUN-REKE (heaven) ni, on ko le sọ nitoripe on ko de ọrun ri ṣugbọn pẹlu ayọ ni on ri w ọ n nibiti nwọn gbe nkọrin "AWA TI GUN S'EBUTE".

## Fashola Di Arinnako

Irohin kan ti a tun gbọ ninu ọsẹ yi ti o y a wa lẹnu niti Ọgbẹni Safi Fashọla ti o jalasi ni Isalẹgangan l'Eko ni ọsẹ ti o kọja. Ọkan ninu awọn ọrẹ kori-kosun rẹ ti o ngbe Agege ni a gbọ wipe gbara ti o ti dakẹ l'Eko ni o ti gba ọdọ rẹ lọ ni Agege wipe ki o tete ba on ṣ e iṣẹ kan ti o ran an, ki o s wa ba on nile l'Eko bi ilẹ ba ti mọ.

Nigbati ọkunrin na de Eko lọjọ keji, ẹkun oku Ṣafi ni o ba awọn ẹbi rẹ ti nwọn nsun; nwọn ni akoko gaan ti o dakẹ l'Eko ni o wa sọdọ rẹ ni Agege.

Fashọla d'arinnako, Ọrunre o

AWỌN OLOOLA WỌ GAWU :-

## Nwon Ni Nwon Ko Gbodo Ko'la F'omo Mo L'Ogbomosho

OGBOMOSHO-Gbogbo awọn oloola (awọn t i nwọn nfi a-nkọ-ila ṣe iṣẹ ṣe ) ni ilu Ogbomoṣhọ ati agbegbe rẹ t i w ọ gawu nisisiyi nitoripe awọn Igbimọ Ibilẹ ilu na ti faake kọri wipe awọn k o gbọdọ ri ki ẹnikẹni kọ ila oju fun ọmọ wọn mọ, ẹnikẹni ti o ba ru ofin tuntun na yio fi pọnun mẹdọgbọn tanran tabi ki o lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹta.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

FEBRUARY MEETING, 1963.

SATURDAY 16TH, 23RD FEBRUARY, 2ND & 9TH MARCH, 1963.

Racing Starts at 3.o.o p.m. each day of the Meeting.

DECLARATION

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30. p.m. and 2. p.m. on Racing Days.

ADMISSION: 3/- PER DAY.

Including Entertainment Tax.

CHILDREN.

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Menbers' Enclosure.

SWEEPSTAKE.

On each day's race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/- and 3rd 10/-.


KO SI A NLỌ ILU OYINBO MỌ

## Awon Odomode Ilorin Se Ipade Lori Eko Giga

ILỌRIN—Ni aipẹyi ni awọn ọdọmọde ilu Ilọrin ninu awọn ti o nkọ ẹkọ ṣe ipade kan ninu ile olori wọn lati jiroro lori irohin kan ti nwọn gbọ lati Kaduna wipe nkan ti o bẹrẹ lati inu ọdun yi lọ, Ijọba Ipinlẹ Ariwa kọ ni ran ẹnikan ninu awọn akẹkọ lọ si ilu Oyinbo mọ lati lọ kọ ẹkọ—giga.

Awọn ọdọmọde na ni irohin na ba awọn lọkan jẹ pupọ, nwọ ni ko n ṣ e wipe owo lati fi kẹkọ giga ni ilu okere bi England, America, Germany a t i awọn ilu Oyinbo miran ti imọ wọn ninu ẹkọ ati iṣẹ-ọwọ jinlẹ, ni ko si mọ lọwọ awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ awọn.

(Wo iyoku loju ewe kej

## Oloye Kosoko Fi Momodu Je Baale Tomi

EKO—Irohin koto afojubi to wiwe lawani oye Baalẹ ilu Tọmu ati agbegbe re ti ọmọba Eko, Oloye Aminu Kọsọkọ, Asiwaju Ọlọja Ereko we fun Oloye Mọmọdu Tiamiyu ni ọjọ Isegun ti ise ọjọ kedogun osu kini ọdun yi, ni aafin Kosọko l'Eko.

Bi ọmọba Eko, Oloye Aminu Kosoko ti guawa repete si aafin re ti o si fe lati se eto fifi Oloye Mọmọdu je Oye nse ni awọn Tọmu ati Ẹbi Oloye Kọsọkọ bẹrẹsi ki lọtun iosi, atewọ si gbojikan nibe. Lehinti awọn ti fi je Oye Baalẹ tan, ni o si sọrọ pe, lati igba iwasẹ ni ilu Tọmu ati agbegbe rẹ ti wa labẹ Oloye Kosọkọ. Awọn ara Tọmu kosi gbọdọ da nkankan se lai gba ase iọwọ olori ẹbi Kosọkọ.

O si dupẹ pupọ lọwọ Oloye Kọsọkọ fun ọla ti o da on, o si se ileri pe, pẹlu igu Ọlọrun on ko ni yi ase rẹ lori Tọmu pada. Oloye Kosọkọ si pa a lase wipe ki ọkan ninu awọn ebi on we Mọmọdu ni lawani oye. Lehinna ti o si fi ọpa oye ti o dara pupọ fun un, o si fun un ni fila onide gidi. O si se ase repetẹ fun Baiẹ na ati awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na, ajẹti ati amuti ni nwọn fi onjẹ adidun ati orisirisi oti ọjọ na se.

Balẹ Tọmu, oye a mọri o; Oloye Kọsọkọ ẹ ku aṣeyẹ.

---

## Awon Ilorin Se Ipade

(O bẹrẹ ewe loju kinni )

Nwọn ni akoko ti awọn sẹse nji giri si ẹkọ yi, ko yẹ ki Ijọba Ipinlẹ awọn fa awọn sẹhin rara. Nwọn ni o yẹ ki nwọn wo bi awọn ara Ipinlẹ Iwọ Orun ati ila Orun ti nran awọn ọmọ wọn lọ si ilu okere fun ẹkọ ti o yege.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


# Eleti - Ofe D'araba




Driving any car with the three pointed star you will experience that special joy shared by Mercedes-Benz enthusiasts all over the world. The joy in perfection, in superb craftsmanship in every detail and in lasting value, in discreet elegance and in the reassuring knowledge of driving in comfort and safety at all times, anywhere.

MERCEDES-BENZ

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB.), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HACOURT, ABA

Sub—Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN. CITY, ONISHA, ABA

# Bawo Ni Olmpio Se Ku Lori Oro Ilu Togo...?(4)

## Awon Alasalu

Nwọn ni bi ko ba nidi obinrin ki jẹ Kumolu. Ọrọ pọ ninu iku ojiji ti awọn ọlọtẹ fi pa Dokita Sylvanus Olympio ni owurọ kutukutu ọjọ Aiku tiṣe ọjọ kẹtala oṣu kinni ninu ọdun yi. Mo ni awọn alasalu lati ilu **Ghana, ti ọtẹ ko jẹ ki nwọn le gbadun ilu wọn, kun ilu Togo, ti nwọn lọ f'ara ṣoko sibẹ. Mo gbọ wipe Ologbe Olympio fẹran lati maa sọọ mọ ọrọ nigba aiye rẹ wipe ẹnikẹni ti o ba ti le sa asala wa si ilu on, On yio dabo boo nibikibi ti o ba ti wa, ti ko ba ti nṣe Ọlọṣa tabi ọmọ jaguda.**

**Ni akoko bẹrẹ ọrọ ofintoto mi lori ọrọ ilu Togo yi, mo fii ye ẹnyin ọkawe** mi wipe awọn ẹgbẹ oṣelu meji lo jẹ pataki ti nwọn nṣe ibẹ ni ilu na, eyi ti ko ba ṣe iketa ni ti awọn ọdọmọde ilu na ti nwọn nje JUVENTO, ẹgbẹ oṣelu ti Olympio ni nwọn si jẹ wọle wọ'de fun ki ede aiyede to wọ ọrọ wọn, ki nwọn to ya lọ ba awọn ọmọ ẹgbẹ alatako (Dẹmọ) ti Ọgbẹni Nicolas Grunitzky, ti awọn ọlọtẹ ilu na wa gbe ipo alakoso ilu Togo le lọwọ lọde oni. Ọrọ wa di mọ wo mi, ki nmọ wo ọ.

### Ota Nla

Awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọmọde ilu Togo (Juvento) na ko gba gbẹrẹ rara, Dokita Olympio paapa si mọ eyi ki o to di ọjọ ti nwọn yio dibo fun lati yan aṣoju wọ igbimọ aṣofin ilu na. Ki awọn enia wọn ba le pọ ti yio wọ ile igbimọ aṣofin ilu na, nwọn da ẹgbẹ awọn ọdọmọde yi pọ mọ awọn ọmọ ẹgbẹ Ọgbẹni Grunitzky ti o nṣe alakoso ilu na loni. Ẹgbẹ Dẹmọ ilu Togo ni nwọn sọ orukọ ẹgbẹ oṣelu ti nwọn.

Mo ni nkan ti o ko ba wọn lọjọ ti nwọn ndibo ni ilu Togo n'i didapọ ti awọn ẹgbẹ mejeji da orukọ awọn ẹgbẹ oṣelu wọn na pọ :: n idibo. Lẹhinti nwọn d... tan nwọn fi oju agba wo nkan ti iwe ofin iṣelu wọn wi, nwọn wa ri wipe awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọmọde yi ti kuna nipa dida pọ ti nwọn da orukọ pọ ninu iwe idibo ti nwọn fi sọwọ.

### Iwadi Nla

**Nkan ti o jẹ ki ede aiyede ti o wa larin awọn ara ilu Ghana ati Togo ko la ni ọrọ gba were, nko gba were ti o ti wa nilẹ. Ni iwọn nkan bi ọdun keje sẹhin awọn apejọ gbogbo** orilẹ-ede agbaiye p'aṣẹ wipe ki nwọn dibo lati mọ ibiti awọn ara ilu ti nwọn npe ni BRITISH TOGO ba fẹ ki nwọn da awọn mọ, bi ilu Ghana ni tabi French Togo ti nwọn ti pa Olympio yi ni.

> ~~LATI ỌWỌ~~
>
> **Olofin Toto**

Nigbati mo nsọ ita rẹ yi, Togo ti Olympio ko ti gba Ominira, abẹ awọn Faranse ni nwọn si wa, sugbọn awọn ara Ghana ti wa ninu Ominira, eleyi jẹ ki ọrọ awọn ara ilu Ghana ki o fuyẹ lọdọ awọn ara ilu British Togo lati wipe ọdọ awọn Ghana ni ki nwọn da awọn mọ.

Ọna ti nwọn fi fẹ ṣe ti awọn ara ilu Ghana nigbana pe meji. Ikinni, anfani ominira ti nwọn ti nri labẹ Ijọba Gẹsi pọ pupọju, nwọn si ri ofin maṣu mato ti awọn Ijọba Faranse nfi jẹ awọn ara awọn ti nwọn wa ni ilu French Togo ni ya. Ọna keji awọn ko le kuro ninu ominira tan ki awọn bọ si oko ẹru awọn Faranse nitoripe awọn ko mọ igbati awọn Oyinbo jagunjagun yio to ju wọn lọrun silẹ ni Togo.

### Ejo N'gboro

**Iyọri idibo ti awọn ara Oke ilu Togo ni ki nwọn da awọn mọ awọn Aganyin Ghana ko tẹ Ologbe Dokita Olympio ati diẹ ninu awọn ara ilu rẹ lọrun rara, nwọn fa ọrọ na titi** sugbọn ẹpa ko boro mọ.

Dokita Nkrumah paapa wa di egungun ẹja o ha wọn lọrun ni ilu Togo, o wa lọ si oke ilu na ti nwọn npe ni Upper Volta, o lọ sọrọ ko ni-tan-nilẹ **kan pe ilu on ni yio jogun ilu Togo ti awọn Faranse ba ti fun wọn ni Ominira ilu wọn ti nwọn ju wọn lokun ọrun silẹ.**

**Gbara ti eku-ida Ijọba ti tẹ awọn ara Togo lọwọ ni** awọn na ba ti nlọ bu atẹ lu gbogbo ọrọ ti Dokita Nkrumah sọ nipa ilu wọn pe ni abẹ on ni gbogbo wọn mbọ wa. nwọn ni ọrọ ti da ko nigbo ko digbo tirẹ mu, ki akọpẹ Ibadan ki o ma kọ t'Iwo. Gbogbo nkan na wa di mọ wo mi, ki nmọ woo lọdọ Dokita Nkrumah, "EJO" N'gboro ilu Aganyin ati Dokita Olompio ti nwọn ṣẹṣẹ gbe alakoso Ijọba ilu Togo le lọwọ nigbana.

### Okun Nle

"Ejo N'gboro ilu **Aganyin (Dokita Nkrumah) paapa ti bẹrẹsi hu iwa okun nle, Aganyin ko wẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ alatako ilu rẹ.** Ọpọlọpọ wọn ni nwọn ti fi ofin gbe lọ si aja-ilẹ. Awọn ti nwọn tete fura sa asala gba ilu Togo lọ la'i fori pamọ sabẹ asia ijọba ilu na.

Ologbe Dokita Olympio paapa yara ṣe ofin if'enia pamọ, o ko awọn ti nwọn le ko ba ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ ti a npe ni Juvento lọ pamọ si ile ẹwọn.

(Koi ti pari)

---

# Nwon Gbejo Fun Awon Adajo Ibile

IBADAN—Awọn alakoso Ijọba tuntun ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Nigeria ngbero lati da awọn adajọ ti o ndajọ ni gbogbo Kotu Ibilẹ duro lẹnu iṣẹ, nwọn ni ko si owo ni apo Ijọba awọn mọ ti awọn yio ma fi san owo oṣu fun wọn.

Minisita alamojuto eto idajọ Ijọba tuntun na Ọgbẹni Webber Ẹgbe ni o sọ ọrọ na firi leti akọwe onirohin wa ni Ibadan ninu ọsẹ ti o kọja yi. Ọgbẹni Ẹgbẹ ni Ijọba awọn fẹ ṣe atunṣe lori ọrọ awọn adajọ na.

Mo gbọ wipe o le ni ẹgbata awọn adajọ ti o wa ni kotu ibilẹ kakiri gbogbo Ipilẹ Iwọ-Orun, awọn isangbe ti nwọn njoko pelu wọn si nlọ bi ẹgba marun (10,000). Owo ti Ijọba Ipinlẹ na nsan lọdun lori awọn kotu ibilẹ na nlọ bi ọkẹ mẹrinlelogoji ponun (£940,500).

**Mo gbọ wipe ṣaju eyi, awọn alakoso Ijọba tuntun ti ṣe ikilọ fun awọn** adajọ kekere wipe iya ti nwọn ni lati ma fi jẹ awọn arufin ti o ba jale pẹẹpẹẹpẹ ko gbọdọ ju ki nwọn bu bi ponun mẹdọgbọn le wọn lori lọ tabi ẹwọn oṣu mẹta ti awọn ko ba ri owo fi tan ọran na. Ọrọ ẹsun ti o ba le pupọ ki nwọn ma fi awọn yẹn silẹ fun awọn ọlọpa Ijọba apapọṣe.

Nwọn ni owo-ori ti ọpọlọpọ awọn Ijọba Ibilẹ miran gbojule wipe awọn yio ma fi san owo awọn adajọ ibilẹ kotu wọn ko to san nkankan.

**Onirohin wa ni on gbọ wipe nwọn ti gbe'jọ fun gbogbo adajọ ibilẹ marun ti o wa ni Ikorodu ati agbegbe ilu na pe nwọn ko gbọdọ ṣe idajọ mọ.**

# ELETI - OFE

ANJUWON KO ȘE WI LEJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

78, Kosoko Street, Lagos. "ELETI—OFE" LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370

VOL XIV. No. 855 SATURDAY FEB. 15 - FEB. 22 1963


# Eko Iparun

AWỌN baba wa a ma pa owe kan bayi ti nwọn ba ri enia ti o sọrọ otitọ ti ko ti pẹhinda ti ọrọ rẹ na ba ṣẹ, nwọn ni Alufa sọrọ ojo ku, o ni Ọlọrun ni o jẹri si ọrọ on. Iyẹn ni ọrọ wosika Olotu iwe irohin Eleti-Ọfẹ laipẹ yi ti o ni ọpọlọpọ awọn tişa Olukọni ni nwọn ti di opurọ ati Onijibiti.

O ni gbogbo awọn ọmọ ti nwọn si nkọ l'ẹkọ paapa ti di awọn ẹniti o nrin leti ọgba ẹwọn lojojumọ. O ni kaka ki o sọ fun wọn ọna jibiti na ni nwọn ngba wọ ile iṣẹ.

Gbara ti Olotu wa ti sọrọ yi tan 'ni awọn Ọga Ọlọpa tẹ iwe irohin ọdun wọn jade fun gbogbo enia ninu eyi ti nwọn sọ wipe ni ọdọdun ni awọn ṣe akiyesi wipe awọn ọdọmọde ti nwọn nwọ ọgba ẹwọn npọ si.

NWỌN ni ko si nkan ti o faa ju oju-kokoro lọ. Nwọn ni iwa oju kokoro na si wọ pọ lọdọ awọn ọdọmọde ti o ṣẹṣẹ jade ilewe ti nwọn gba wọn si ibiṣẹ le-owo bi Banki tabi ṣọbu.

ẸNYIN obi, ọrọ re o ! Ṣe a ti sọ fun yin wipe nigbagbogbo ni ẹnyin alara paapa nfi iwa yin ṣe apẹrẹ ọkanjuwa fun wọn. Ẹ ko fi ọna bi a ti nṣe iṣẹ pẹlu itara kọ wọn, a fi bi a ti le ṣe imẹlẹ ki a fi ọna eru ko owo jọ.

NITOTỌ ọpọlọpọ enia ni "KO WA 'SAIYE TI O le" a fi aiye ki nwọn fẹwọn logba.

Ẹniti o ba fẹ ki o gbọ waasi awa "Eleti—Ọfẹ", awa ti sọ tiwa na.

# Mbu Lo Si Geneva

EKO- Ọgbẹni M. T. Mbu, minisita alamojuto eto awọn ọmọ ogun oju omi ti Ijọba Nigeria ran lọ si ilu Togo ni aipẹ yi lati pẹlu awọn ikọ orilẹ ede marun ṣe iwadi iku ti o pa Dokita Olympio. Awọn ṣọja ilu Togo ti faake kọri wipe awọn ko fẹ ọrọ ẹnkuarl kankan ni ilu awọn, Ọgbẹni Mbu ti pada wa si ile, nwọn si ti tun ranişẹ gba ilu Geneva lọ. Ẹ o gbọ irohin bi nkan ti nlọ ni ilu Togo lọse ti mbọ ninu Eleti Ọfẹ.

# Iwe Si Olotu

## Oro Kanpeni To Ogbeni!

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe yin lati kin ọkawe yin ti o nje ỌMỌMEJI lẹhin nipa ọrọ kanpeni ti o ni Ọgbẹni (Lọya) R.A. Fani-Kayọde ti nwọn ṣẹṣẹ fi jẹ Minisita alamojuto eto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nṣe kakiri gbogbo ibi ti o ba nlọ ni Ipinlẹ na.

A fẹ ki ẹ ba wa tẹ mọ Ọgbẹni Fani-Kayọde na leti wipe a ko fẹ gbọ ọrọ kanpeni (Campaign) kan rara lati ọdọ rẹ nisisiyi a fi bi o ti ṣe ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun wa ti gbogbo enia ti fi nṣe iranwo yio tun pada si ipo iyi rẹ ti atijọ, ti aiye a roju ti aya gbogbo awa ara ilu yio si ba lẹ.

Kinni Ọgbẹni Fani-Kayọde fẹ sọ fun wa nisisiyi ti awa ti a wa loko tabi larin ilu ko ti gbọ ri ? A ki ṣe ọmọde, gbogbo irọ ti awọn oṣelu wa ma npa ni awa na ti mọ. Tabi nwọn ṣẹṣẹ tun gbe irọ gba-ko-fi-sọgbọn kan de lati ọna oke Okun ni ? Nitoripe a ti mọ pe ki su wọn kisi rẹ wọn rara lati ma gbe irọ nla nla wa ta fun wa lati ọna ilu miran.

Eleyi su wa, ọrọ KANPENI to Ọgbẹni. Ọrọ bi ilu wa yio ṣe ma lọ si iwaju ni a nfẹ.

Emi ni,
S Aralamọ
Ọlọrunda,
leti Ilaro

### Iwe Enia Ti A Ka Da?

Olotu, mo gbadun yin, mo si kan saara si yin lọpọlọpọ tun ọrọ yin ti o jade laipẹ yi ninu iwe Eleti-Ọfẹ nibiti ẹ gbe ti nni awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe wa ni Nigeria leti wipe iwe enia kika (census) ti nwọn ti ṣe ileri wipe awọn yio gbe sita da lati ọjọ yi.

Kinloṣe ti awọn ti a gbe Ijọba wa fun na le lọwọ wipe ki nwọn ko mọ ba wa ṣe alakoso rẹ feran lati ma fi ọbọ lọ wa? Ṣe nwọn lero wipe a gbagbe ọrọ enia ki ka yi ni?

A ko gbagbe rara, a nsọ wọn lọwọ ati lẹṣẹ nipa ọrọ enia kika na (census) na ti nwọn ti fi bi ọdun kan ka ti nwọn ko tẹ gbe jade nitoripe nwọn fẹ sọ wipe awọn ara ibikan lo pọju awọn ara enia kan lọ.

Olotu, 'aşiri wọn titu, irọ ni nwọn npa.

Emi ni,
E. A. Adewale
Kemta,
Abẹokuta

### Tisa Opuro

Olotu, mo gba fun ọrọ yin ti e kọ laipẹ nipa awọn Olukọ ile iwe wa ti nwọn ki nṣe Ododo ninu ẹkọ ti nwọn nkọ awọn ọmọ wa nipa apẹrẹ iṣẹ jibiti ati wayo ti awọn na nṣe lojujumọ.

Otitọ ọrọ ti e sọ na jade ninu iwe irohin awọn Ọlọpa ti nwọn tẹ jade ninu oṣu yi. Nwọn ni lojojumọ ni awọn ọmọ ilewe ti nwọn ba ṣẹṣẹ gba sibi iṣẹ nhuwa ẹlẹwọn.

Ẹnyin Obi, ẹ kọ awọn ọmọ yin lọna lati maṣe Olotiọ nibi iṣẹ wọn.

Emi ni,
S. Salako
Ijero,
Ebute-Metta


# E polowo

**Oja yin sinu Iwe Irohin Eleti—Ofe losose.**

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Egbe Olomi

Loju temi, o dabi eni wipe awọn ara mi l'Oke-Ọya, awọn ọmọ ẹgbẹ OLOMI (NPC) ti ọpọlọpọ awọn enia nfi oju kekere wo mọ nkan ti wọn ni lati ṣe ni BONKẸLẸ. Mo ri to ki emi Ayiluka to sọ ọrọ yi jade. Ọlọla Amọdu Bello, baba ẹgbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi ti tun ṣe alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna ko gba gbẹrẹ rara. Bi o ti npa ẹran lojọ Alamisi bẹni o nfi owo ṣe saara lojọ Jimọ o si ngbawẹ lojọ Laadi (iyẹn ni ẹnyin Yoruba npe ni ọjọ ọsẹ.)

### LATI OWO AYILUKA

O ni eleyi ko to, o ko s'ọkọ, o lọ ṣe "KUNKARI" pẹlu awẹ ni ilu Mẹka fun ọjọ meje gbako. Bi ẹ ba sọ wipẹ kinni o fa a ti ko ṣe jẹki ọrọ "kunkari rẹ na di igbati gbogbo enia nlọ si Mẹka; ma da yin lohun wipe Ọlọla Sadauna kiṣe ọbọ idere, mo ti mọ ọ tipẹ.

## "Pelu Kunkari"

Ẹniti o ba lọ si ilu Mẹka ni asiko tı gbogbo enia nlọ, iran nkan ti Ọlọrun ṣe saiye ni oluwarẹ lọ wo, ko lọ ṣe "kunkari" rara.

Ẹnyin ọrẹ mi, ọrọ pọ ninu "kunkari" yi. Awọn Yoruba ni agbalagba ti o nsare ninu ọgan ẹkaan ko nṣe lasan, bi ko ba nle nkan, a jẹ wipe nkan lo nle e, iyẹn ni ọrọ ti Ọlọla Amadu Bello na.

Face your future with

CONFIDENCE!

Life is full of uncertainties, but what's the best way to face your future with confidence and feel safe and secure?

Insure your life now, thereby safeguarding and protecting your family's future on a low-cost policy from:

Great Nigeria Insurance Co. Ltd.

(Incorporated in Nigeria)

HEAD OFFICE: 39/41 MARTINS STREET LAGOS. PRIVATE MAIL BAG 2314, TEL. 25251

Branches:- WRFC Building, Lebanon Street, Ibadan 151A Folagbade Street, P. O. Box 133, Ijebu-Ode, Telephone 82 Ibara Road, Abeokuta,

## Temiyemi

Alakoso Ijọba ni ilu Afrika ti o ba so wipe eru aiye ko ba on bi nkan ti nlọ si misisiyi, o parọ ni. Oni a gbọ wipe awọn pa Olympio ni Togo, ọla nwọn sọ bọmbu si moto Nkrumah ni Ghana. Ọtunla a gbọ wipe awọn ọlọtẹ yinbọn pa alamojuto Ijọba Iraq. Eleyi na to ki enia lọ ṣe "kunkari" loju orori Anabi bi oluware ba fẹ fọwọ rọri sun ninu eyiti a wa yi.

Ọlọla Amadu Bello, ọmọ ọba Sokoto, ọmọ o fi kunkari di nkan mu; mo gbadun rẹ! Tire ye ẹ!

## Oni Bara Kano

Emi Ayiluka gbọ wipe iṣẹ bara ti di iran fun awọn kan ni ilu Kanọ! Nwọn ni ko digbati oju ba fọ ki nwọn to gbe igba bara, ofin ni; baba nṣe, iya nṣe, ọmọ nṣe, ana paapa nṣe. Wahala awọn oni bara (alagbe) na wa pọju ninu awẹ yi, ti awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Kano fi gbe agogo sita wipe awọn ko gbodo gburo awọn onibara yi ni alẹ ati lakoko SARI loja titi ni Kano mọ.

Njẹ iru ofin alalafia bayi le lọ ni ilu Eko wa yi? Ẹ jẹ ki a bi Ọlọla wa Tafawa Balewa lere, on ni alaṣẹ gbogbo wa, ati Olowo ati onibara.

Mọ gbọ wipe ko si ibiti awọn onibara pọ to ninu ile aiye ti o to ti Eko; nwọn jẹ SERIKI, nwọn jẹ Iya-Adini. Ti o ba fẹ ja mi ni irọ ti o ba di alẹ ọjọ Alamisi ki o wa woran n'i Ereko, ariwo "dere Jimọ" ni a diẹ leti, bi o ba si nwa mọto, o ni lati dẹ ẹ ki o ba ma gbe oku Mallam Maikafo (afọju lo njẹbẹ).

## Alaso Ereko

Enyin obinrin ti ẹ nta aṣọ l'Ereko, emi Ayiluka ki nyin, ẹ ku ipalẹmọ ọja ọdun Awẹ. Mo ti ri ọpọlọpọ awọn alejo onibara yin obinrin ti nwọn ntu wọlu lọwọlọwọ. Mo si ti ri ọpọlọpọ yin ti o ntun ṣọbu wọn kun lọda; awọn ti ko ni ṣọbu ntun ipatẹ wọn kan ni onilegogoro. Ṣe ẹnyin na mọ wipe emi Ayiluka ko le ri nkan ki nma sọ.

Mo gbọ wipe aṣọ-tuntun ti ẹ fẹ gbe jade fun awọn onibara yin fun ọdun Awẹ ti de, orukọ suna ti e o fun un ni ẹ si nro. Ẹnyin ọmọ ẹgbẹ MẸṢỌ ati ỌMỌDE MẸTỌ, iyoku di ọwọ yin. Ẹ o ma tun gburo emi Ayiluka ninu ọsẹ ti mbọ. Ẹ ku iṣẹ lada, ẹmi gbogbo wa yio gba awẹ na ja o.

## Awon omo Tanganyinka ti o lo fun eko-ofe ni ilu Oyinbo.



# Itan Oba Alake Ademola Keji

## ( Lati Owo Omo Abati)

### Ago-Owu, Abeokuta

Ninu itan mi ni ọsẹ ti o kọja mo sọfun ẹuyin ọkawe mi wipe awọn ọmọ Ẹgba ni awọn ti o mọ eto orin kikọ ṣe ninu awọn ọmọ wọn. Awọn ọmọ Ẹgba ni o kọ laju si a nlọ si ilu Oyinbo lati lọ kọrin sinu awo gbohun-gbohun ti nwọn npe ni gramophone record ti o di yẹyẹ ni Nigeria ni ode ti isisiyi.

Ologbe alufa J.J. Ransome-Kuti jẹ ẹniti o fẹran orin pupọ, o si ṣe atofọ orin Yoruba pupọ nigba aiye rẹ. Bẹna - na si ni ọmọ rẹ "Dawodu" Ologbe alufa I O Ransome Kuti tiṣe Oluko ilewe giga ni Igbein ni Abeokuta nigba aiye rẹ. Orin meji ni Pa Kuti fun awa Ẹgba gẹgẹbi orin ibilẹ (National anthem) ni iwọn ọdun mẹtalelogoji sẹhin. Ọkan ninu meji na ni mo tẹ jade fun nyin ninu iwe itan mi ni ọsẹ ti o kọja. ikeji ni eyi:

(1) Kabiyesi Ọba Alake
Ademọla Keji,
Ọmọ Erin Jogunọla,
Ọmọ Ọtẹnkan,
Kabiyesi! Kabiyesi!!

2) Awa ewe Abẹokuta,
A yin 'Luwa logo,
Fun anu ati ore rẹ si Ọba
Ademọla,
A si nkọrin ogo,
Ogo! Ogo!!

(3) Fi ẹbun ati ore Ọfẹ Rẹ
Tẹ Ọba wa lọrun,
Ki ade ko pẹ lori rẹ,
Ki bata pẹ lẹsẹ,
Ki a si ma kọrin,
Kabiyesi.

Eyi ni ikeji orin ti Eniowo Ologbe Alufa J J Ransome-Kuti kọ awa ọmọ Ẹgba ti a nlọ si ile-iwe nigbati nwọn gbe ade fun Ọba wa Alaiyeluwa Ademọla Keji ni 27th September 1920-ọdun mẹtalelogoji nisisiyi. Nigbana awọn ọlọpa onifere ilu Ẹgba ko ṣe fi ara we rara. Ati ọmọ ilewe pẹlu awọn akọrin Ọlọpa yi ti nwọn npe oruko wọn ni E.N.A. Police Band ni nwọn jọ kọ ni orin yi pọ.



### Orin Kuti

Orin yi duro fun gbogbo awa ọmọ Ẹgba bi orin God Save the King ti duro fun awọn Gẹsi ti nwọn ba nyẹ Ọba wọn si nibikibi. Gbogbo awọn ọmọ Ẹgba igba ọjọ na lọhun ni nwọn mọ awọn ohun ti nwọn kọ wa lati fi kọ awọn orin ibilẹ Ẹgba mejeji na.

A lo ohun ti atijọ yi fun iwọn ọdun mẹrindinlogun gbako ki "Dawodu" Ologbe Alufa I. O. Ramsome Kuti to de ti o si fun awọn ọmọ ile iwe ilu Ẹgba ni orin ati ohun tirẹ ni iwọn mejilelọgbọn sẹhin.

Ologbe Alufa I. O. Ransome Kuti jẹ ọmọ bibi inu Alufa J. J. Ransome Kuti, alufa Ijọ Ṣọsi C.M.S. ni Ake l'Abẹokuta. Ọpọlọpọ ọdun ni alufa Kuti fi ṣe iṣẹ tiṣa-agba ni ile iwe giga ti a npe ni Ijẹbu-Ode Grammar School ni Ijẹbu-Ode. Ọpọlọpọ awọn ọmọ Ijẹbu ti o di enia pataki pataki ni aiye oni ni alufa Kuti ti kọ ni iwe.

O pada si ilu Abẹokuta ni iwọn ọgbọn ọdun si igba ti a wi yi, ọdun keji lẹhin na o wa kọ orin kan (gẹgẹbi ologbe baba rẹ) fun gbogbo awọn ọmọ ile iwe ilu Ẹgba ti nwọn nilati ma a kọ fun ẹyẹ fun Ọba Alake nibikibi ti awọn ọmọ ile iwe na ba mba ṣe ẹyẹ. Eleyi ni ọrọ orin ti "Dawodu" na.

**This is picture of James Cairncross will appear in the three plays which Nottingham Playhouse company will produce on the West Africa tour starting in Jan. In Twelfth Night, he will play Sir Toby Belch.**

(1) Kabiyesi Ọba Alake
Ademọla Keji,
Ọmọ Erinjogunọla,
Ọmọ ọtekan,
Kabiyesi Ọba wa, Kabiyesi (2ce)

(2) K' Ọlọrun Ẹgba ko toju yin,
Ninu itobi Rẹ,
Kọjọ nyin dọjọ alẹ,
Kaya ilu balẹ,
Kabiyesi Ọb wa, Kabiyesi (2ce)

### Ijaiye

Boya ni a le ri ninu awọn adajọ, lọya, Dokita, awọn oṣelu pẹlu awọn enia pataki lọkunrin ati lobinrin ti nwọn kọ ẹkọ iwe ni ilu Abẹokuta ni iwọn ọgbọn ọdun sẹhin ti nwọn yio wipe awọn ko mọ ohun orin yi. "Dawodu" ọrun rẹ'!

Gẹgẹbi mo ti sọ ninu itan mi ni ọsẹ ti o kọja wipe orin "ADEMỌLA JỌBA ILU TORO NINI"ni orin pataki ti awọn Ẹgba kọ lọjọ ti nwọn ngbe ade fun Alaiyeluwa Ọba wa na; awọn ỌMỌ IJAIYE ni o kọ orin na.

Ko si ẹniti o le wipe bawo ni ti awọn ara adugbo ti a npe ni Ago-Ijaiye ni Abẹokuta ti ri ni Afin Alake, nitoripe Ologbe Ọgbẹni PẸLU Onilu ni agbole Adan ni Ijaiye ni Onilu Ọba Gbadebọ nigba aiye rẹ, on na ni o si lu ilu gangan lọjọ ti Ọba ngbade. Aburo rẹ, Akanni, ni onilu Ọba Oshinle Karunwi ti awọn Ẹgba pa ni Ọba ni 1918 ninu Ogun Adubi. Ilu ati orin mbẹ lọwọ awọn ọmọ Ijaiye.

(Koi ti Pari)

OLOYE BAYO DOHERTY



Oloye T. Adebayo Doherty baba ẹgbẹ ẹgbẹ Akọya fun ilu Eko.

Ẹniti anbuku ti Oluwa N'bukun

Kingsway

## STARTS ON TUESDAY FEB. 19th.—23rd.

# FEBRUARY Features

Men's CREAM SHIRTS 20/-

## 2,000 Van Heusen SHIRTS 32/6 Ends of ranges

### MENSWEAR

Wool PULLOVERS 45/-

All Wool SLIPOVERS 32/6

SOCK BARGAINS
Stretch Nylon Short Hose 4/-
Stretch Nylon Half Hose 4/6
Stretch Nylon Fancy Hose 4/6
NYLON Golf Hose 6/-

*TREMENDOUS BARGAINS IN MENSWEAR*

### CHILDREN'S

Children's CARDIGANS 25/-

SPORTS SHIRTS 13/6

*NYLON ANKLE SOCKS 2/-*

Girls Cotton SKIRTS 15/-

ROMPERS 7/6

*CHILDREN'S DRESSES 10/-, 20/-, 30/-*

Boy's Shirt & SHORT SETS 10/-

*'Dandy Step' SHOES 15/-, 20/-*

LADYBIRD 'T' SHIRTS 7/6

### LADIES

*DRASTIC REDUCTIONS IN COTTON DRESSES*

PLASTIC RAINCOATS 12/6

Cotton Vests 5/-

"Miss Triumph" NYLON BRAS 7/6

DRESS FABRICS from 4/6 yd.

*"High Life" BLOUSES 10/-*

CARDIGANS 32/6

*NIGHTDRESSES & PYJAMAS 25/-*

EVENING HANDBAGS 15/-

### HARDWARE

Stainless Steel CUTLERY
Table Knives 2/3
Table Forks 1/-
Table Spoons 1/-
Tea Spoons 9d.

*SUITCASES TO CLEAR 45/- to 75/-*

3 BURNER COOKERS with 2 ovens £16-10-0

4 pce ENAMEL STEWPANS 18/- set.

WONDERFUL BOOK BARGAINS

*Vases, Jugs, Ash Trays Candle Sticks from 1/- ea.*

### HOUSEHOLD

*COTTON FURNISHING FABRIC 8/6 yd.*

TERRY TOWELS 7/-

MOSQUITO NETS 40/-

CARPET SQUARES
67" x 94" £17-0-0
7½ x 3yds [illegible]
3 x 4yds [illegible]

*WILTON & KOSSET CARPETS Heavily Reduced*

"HOME STAR" CARPET Reduced to £5 [illegible]

**KINGSWAY STORES OF NIGERIA LTD., P. O. BOX 562, LAGOS.**

### Awon Oloola Wo Gawu

## Nwon Ni Nwon Ko Gbodo Ko'la Fomo Mo L'Ogbomosho

Gbogbo ẹsẹ awọn ara ilu ati Ọba Sọhun Ogbomọshọ Ọba Ọlatunji Elepo Keji ni nwọn pe sibasiba si ibi ipade ti nwọn ti ṣe ofin yi ni ọsẹ ti o kọja, Ọgbẹni Victor Lajide ni o si ṣe]alaga ipade igbimọ ọjọ na.

Nwọn ni bi ofin yi ti ba awọn obi ọlọmọ w ni o tun ba awọn oloola paapa wi; ẹnikẹni ninu awọn oloola ti o ba tun ba wọn kọla soju ni Ogbomọshọ yio lọ sẹwọn tabi ki Ijọba Ibilẹ gba pọnun mẹdọgbọn owo-ọran lọwọ rẹ.

Gbogbo awọn ara ilu ati awọn ijoye ni nwọn n[i] awọn lọwọ si ofin tuntun na. Onirohin Eleti-Ọfẹ ni on gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ ti o wa nile ti kọwe si awọn ara wọn ti o wa ni i dalẹ bi Ghana, Minna Zunguru, Zaria, Jos, Kaduna ati Kano nipa ofin na wipe ki nwọn ye kọ ila-oju fun ọmọ wọn mọ nitoripe aṣa na ko ba aiye ode isis yi mu.

# Awon Omo Ilorin Se Ipade

(O bẹrẹ loju ewe Keji)

Onirohin wa ni awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ na ti ṣe ipinnu lati fi iwe-ẹbẹ ranṣẹ si Minisita alamojuto eto ẹkọ ati Ọlọla Amadu Bello, Sadauna Ṣokoto tiṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna wipe ki nwọn ba wọn wo ọrọ na ṣe.

Nitotọ laipẹ yi ni Alhaji Umaru Babura, Seriki Fulani Jaidanawa, ti ṣe Minisita alamojuto ile ikọṣẹ ati eto ifini siṣẹ ṣe ikilọ kan ni ipade awọn aṣoju Ijọba ti o nyan enia fun ẹkọ ọfẹ, pe Ijọba Ipinlẹ awọn ti fake kọri wipe awọn ko ni ran enia kankan ninu awọn akẹkọ lọ si ilu Oyinbo mọ nitoripe awọn ti ni ile ẹkọ giga julọ (Universities) to ni ilẹ yi nibiti nwọn gbe ti le kọ enia ni oriṣiriṣi iṣẹ ati ẹkọ ijinlẹ.

Mo gbọ wipe ninu ọdun yi, igba (200) enia pere ni awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Ariwa fẹ fun ni ẹbun afani ẹkọ ọfẹ ninu awọn akẹkọ ọmọ wọn lọkunrin ati lobinrin. Awọn enia merindinladọta ni nwọn de lati ilu Oyinbo ninu awọn ti nwọn ti fun ni ẹbun ọkọ-ọfẹ ti nwọn si ti yege ninu ẹkọ ti nwọn ran wọn lọ kọ na.

Akọwe agba kan fi ye mi ni Kaduna pe ninu awọn igba enia ti nwọn nwa lati fun ni ẹbun ẹkọ-ọfẹ, nwọn ti ri to ọgọsan (180) awọn akẹkọ nisisiyi ti nwọn nyẹ ọrọ wọn wo lọwọ lati ran wọn lọ kọ ẹkọ n ile ẹkọ giga (University) kakiri.

Awọn Ijọba ilẹ Arab ni ki nwọn ran awọn ọmọ mẹtala wa ki nwọn kọ wọn lẹkọ lọfẹ; awọn Ijọba ilu Mẹka ni awọn fẹ ki nwọn fi ọmọ akẹkọ Ariwa mejidinlogun ranṣẹ si awọn fun ẹkọ-ọfẹ.

# Irohin Agbaiye

## Jidda

A gbọ wipe ki Alakoso Ipinlẹ Ijọba Ariwa, Ọlọla Alhaji Amọdu Bello, Sardauna Sokoto to kuro ni Mẹka ti o ti lọ ṣe "kunkari" (etutu) ni ijẹta awọn alamojuto ile ẹkọ giga ti nwọn npe ni Jẹdda University fi oye olori ile-ẹkọ giga na daa lọla, o si di ẹniti yio ma ba wọn ṣe ajọhun lori eto ile-ẹkọ na. Iyẹn ni wipe ẹniti o ba fẹ lọ kọ kewu ijinlẹ nibẹ, Ọlọla na wa ninu ẹniti o le fọwọ sọ'ya fun un.

Ọba Ṣokoto pẹlu Ọba Ilọrin ti nwọn ba Ọlọla Amọdu Bello, Sardauna lọ si Mẹka ti pada si ilu wọn lana.

## Oba Ifon Waja

Anu ṣe wa lati tufọ Ọba Olufọn Joseph Oyinbo Mabo Keji, ni ilu Ifọn ni Ipinlẹ Iwọ-ornn ti waja lọsẹ ti o kọja yi, ẹni ọdun mẹtadinlọgọta ni, o si jẹ oye fun ọdun mejidinlọgbọn, gbako, on si ni alaga Igbimọ ibilẹ ti nwọn npe ni Ẹkamarun ni agbegbe ilu wọn.

Adajọ kotu ibilẹ ni, iyawo mefa ni Ọba na ni, o si bi ọmọ mẹtadinlọgbọn, ọkan ninu wọn ni Ọgbẹni Oye Mabo ti nṣe akọwe ile Igbimọ Ẹkamarun ni Ifọn. Awa Eleti - Ọfẹ ki awọn ọmọloku na, awọn ku aṣẹhinde.

# Eleti —Ofe Da'raba

RECORDS OF THE WEEK

R.P.M. at 6/9 each
P.382517 F
Mo Nsa Cha-Cha-Cha/
Wamma'A'Mewu
P.382518 F
Yeda Wo Ase Osagyefo/
Abibiman Akuafo
E. K.'s Band
P.382537 F
Da Temeye Bom/Mama
De Kumba
Mayor's Band of Onitsha
P.382543 F
Urho Kuosa/Ai Mieno Oh
Paul Ede and His Group.

PHILIPS
of course...
—the records of the century—
Philips (Nigeria) Ltd.
Head Office: P.M.B. 1136
Apapa
Branch Office: P.O. Box 429
Enugu

## Ojora Goke Agba

Irohin kan ti a gbọ ni ana ni irohin aladun ni ti Ọgbẹni Adekunle Ọjọra ti o ti nṣe alajọhun fun awọn Oyinbo onisọwo U.A.C. ri, ti nwọn tun wa sun ipo rẹ siwaju si, ti nwọn sọ ọ di Onimọran fun gbogbo awọn alajọhun (Public Relations Managers) ibiṣẹ UAC ti mbẹ ni Nigeria jake jado.

A gbọ wipe Ọgbẹni Ọjọra ni awọn Oyinbo onisowo yi kọ fi iru ipo oga iṣẹ bayi da lọla ati pe ni Ipinlẹ kọkan ti nwọn ni awọn alajọhun si, awọn enia dudu ni nwọn fi sori aga. Adekunle, wa pẹ nibẹ o o!

Printed and Published by The Union Printing & Publishing Company 28, Kosọkọ Street Phone 23370 Lagos
Editor (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.